# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Ketala: Osu Keta Ojo Kerindinlogbon, 2017**

**Akori Oro: Iberu Olorun** – Apa Kini

**Eko kika: Romu 3: 9-18**

## Afihan

Arakunrin ati arabinrin ninu Oluwa, nje e beru Olorun? Mo mo wipe olukuluku ni yio wipe awon beru Olorun; sugbon ko si enikankan ninu wa ti o beru Olorun, ore-ofe ni a fi ngba-wala. Idi ni wipe niwon igbati eda-enia nse elese ati oluse-ibi, a ko beru Olorun. Bi o tile je wipe, ninu aiye loni opo enia ni nwon nlakaka lati beru Olorun, ki se wipe nwon beru Olorun, sugbon nwon nlakaka lati beru Olorun ni.

Larin eko yi, olukuluku wa yio riran ri ara re, ao si mo ibiti a ku si; sugbon mo gba wa ni imoran wipe ki a tun ibiti a ku si se, nitoripe "Eniti a ba nbawi ti o wa orun ki, yio parun lojiji laisi atunse" **Owe 29: 1**. Lehin igbati o ba ti ko ipa ninu eko yi, bi o ba ko lati gbe awon igbese atunse, ko tun si atunwi asan mo; besini iwo ki yio wa bi alai-lebi ni iwaju Olorun.

## Awon enia ti so iberu Olorun nu

Ara, iberu Olorun ni o sonu ninu aiye loni, eyi ni o mu ki aiye polukuru-musu, ti ohun gbogbo ko si lo dede mo. Toripe ko si iberu Olorun, **awon omo ko bowo funawon obi nwon mo,**besini awon obi paapa nfi awon omo nwon wa owo ni awon ona ti ko bojumu; ti nwon si nlo awon omo lodi nitori owo.

**Iberu Olorun sonu larin oko ati aya**, eyi ni o mu ki opolopo igbeyawo ma tuka ni alai-tojo. Awon aya ko bowo fun awon oko nwon gegebi o ti ye; besini awon oko paapa ngba satani laaye lati fi nwon ba awon aya won ninu je, ti nwon si nwa isubu awon aya won.

**Iberu Olorun sonu larin ore si ore**, debipe awon enia npowe wipe "ore kosi mo, ki a wa eni ba rin loku". Ore njowu ara won, won si nse ilara pelu ipinnu-ibi si ara won.

**Iberu Olorun kosi ninu opolopo ijo,** nitori re ni awon asiwaju won se nfi awon olujosin sinu igbekun nipa ti Emi ki aiye ti nwon ba le tesiwaju. Larin awon omo-ijo, ife-oju ni o poju, ti nwon nfi eje sinu ti nwon si ntu ito fifun jade.

**Larin orile-ede si orile-ede iberu Olorun sonu,** ohun ni o jeki awon orile-ede ni agbaiye ma fi etan ba ara won lo, ti won kosi le so oju abe ni'ko tabi so ododo.

Bibeli fi idi re mule wipe Iberu Olorun ko si ni iwaju awon enia. Awon enia ko ni iberu Olorun rara **Romu 3: 18, Orin Dafidi 36: 1**. Ara, kini se ti a ko fi aye gba iberu Olorun lati gbile ninu okan wa? Niwon igbati Olorun ti kede wipe "Awa ni iran ti a yan, olu-alufa, orile-ede mimo, enia oto…." **1 Peteru 2: 9**. E jeki iberu Olorun mu awon enia ri iyato ninu iwa yin, ise yin ati oro siso yin ninu aiye, ki gbogbo enia le yin Olorun logo lati ara yin; ki won si fi iyin fun oruko re mimo.

## Itumo iberu Olorun

Ni igbakugba ti a ba nsoro nipa iberu Olorun, ohun ti awon enia ma nwi nipe ohun ni ipilese ogbon, imo ati oye; sugbon ao soro ni kikun lori re loni.

**Ipilese imo:** Opo ninu wa yio wipe niwon igbati iberu Olorun ti je ipilese imo, bi on ko ba ni iberu Olorun, imo nikan ni on yio padanu; sugbon iru awon enia wonyi kuna. Asiwere, iwo ko mo wipe emi re nbe ninu ewu. Aini iberu Olorun ti fi opolopo kristiani sinu ajaga ati ide loni **Owe 1: 7**. Iru awon enia be ni asiwere ti nwon gan ogbon ati eko, awon wonyi yio segbe gegebi iwe mimo ti wipe " A ke awon enia mi kuro nitori aini imo: nitori iwo ti ko imo sile, emi o si ko o, ti iwo ki yio se alufa mi mo; niwon bi iwo ti gbagbe ofin Olorun re, emi pelu o gbagbe awon omo re" **Hosea 4: 6**. Bi o ko ba fe ki Olorun gbagbe re, bi o ko ba fe ki okunkun segun re, beru Olorun loni.

**Ipilese ogbon:** Iberu Oluwa ni ipilese ogbon: oye rere ni gbogbo awon ti npa ofin re mo ni; iyin re duro lailai **Orin Dafidi 111: 10**. Torina, beru Olorun, ki o si pa awon ofin re mo. Bi o ko ba beru Oluwa, o je alai-logbon enia, bi eyi ba si sele; o je wipe asiwere ni o **Oniwasu 10: 3**.

Iberu Oluwa ni ogbon, ati lati jade kuro ninu iwa-buburu eyi ni oye **Jobu 28: 28**. Bi o ba nfe lati ni iberu Olorun, o ni lati ko satani ati awon ona buburu re sile. Sa kuro ni awon ona ibi, yipada si Olorun, ki o si ba laja. Ni ipinnu lati isisiyi lo wipe iwo yio ma se awon ohun ti inu Olorun dun si, ki o ba le ri Ile-ologo wo.

Iberu Oluwa li eko ogbon; ati saju ola ni irele **Owe 15: 33**. Awon ti won beru Olorun nikan ni won gbon, enikeni ti ko beru Olorun asiwere ni. Iru awon asiwere enia yi ni Bibeli wipe nwon wi li okan pe "Olorun ko si" **Orin Dafidi 14: 1**. Bi o tile gbagbo wipe Olorun mbe, bi o ko ba beru re, asiwere ni o. O wa ni abe ojiji-iku,

onitohun si le ku ni aitojo tabi ki o ku ni rewe-rewe, nitorina beru Olorun.

Iberu Oluwa ni ipilese ogbon: ati imo Eni-Mimo li oye **Owe 9: 10**. Gbogbo okan ti ko beru Olorun ko ni imo re, iru awon enia yi ntan ara won ni; nitoripe imo Olorun kise wipe ki a ka Bibeli tabi ki a mo awon ese bibeli nikan. Iru awon wonyi je asiwere ati alailogbon, nwon si le ku nitori ailogbon won ni Bibeli wi **Owe 10: 21**.

**Ikorira ibi, irera ati igberaga:** Iberu Oluwa ni ikorira ibi: irera ati igberaga, ati ona ibi, ati enu arekereke ni mo korira **Owe 8: 13**. Gbogbo kristiani ti ko ba korira ibi, ko ni iberu Olorun, besini isin ati esin awon wonyi je asan. Bi o ba ro ibi ninu okan re tabi o fi aye gba ise-ibi, o ko beru Olorun. Kosi iye igba ti o le gbadura, ati iye ojo ti o le fi gba awe, ayafi ti o ba ko irera ati igberaga sile; o ko beru Olorun. Ranti wipe irera ati igberaga ni o mu ki Lusiferi so ipo re nu **Isaiah 14: 12**. Ona kan soso ti o le fi kuro ninu ibi, ki ibi masi se sele si o, ni ki o beru Oluwa **Owe 16: 6**. Niwon igbati o je wipe iberu Oluwa ni o le pa o mo kuro ninu ese ati ibi, ni iberu Oluwa nisisiyi. Awon igbese ti ao menuba ni o nilo lati beru Olorun:

- Pa ahon re mo kuro ninu ibi ati ete re kuro li etan siso.
- Lo kuro ninu ibi, ki o si ma se rere; ma wa alafia, ki o si ma lepa re.

Nigbana ni iwo yio ni iye, aseyori ati ojo pupo ninu ire **Orin Dafidi 34: 11-14**.

**Orisun iye:** Iberu Oluwa ni orisun iye, lati kuro ninu ikekun iku **Owe 14: 27**. Okankokan ti ko beru Oluwa emi nwon ko jo won lo'ju, nigbati o je wipe bi o ba beru Oluwa o ti re iku koja sinu iye. Bi o ko ba fe ku lai-tojo, bi o ba fe di agba, ki o di arugbo, akoko niyi lati ba Eleda re laja, ki o si beru re.

Iberu Oluwa te si iye: eniti o ni i yio joko ni itelorun; a ki yio fi ibi be e wo. **Owe 19: 23**. Beru Olorun ti o ti wa pelu re lati ojo-asepo awon obi re titi di oni, Olorun ti ko je ki odo-aiye gbe o lo, ni o ye lati beru. Bi o ba nfe ifokanbale ati idabobo kuro ninu ewu, o ni lati beru Oluwa.

**Iberu Olorun je Mimo ati pipe titi lai:** Iberu Oluwa mo, pipe ni titi lai. Iberu Oluwa je ohun Emi, ti ko ni adalu, ti ki isi dibaje; nitorina ni igbona-okan lati beru Oluwa, nitori idajo Oluwa li otito, ododo ni gbogbo won **Orin Dafidi 19: 9**.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Kerinla: Osu Kerin Ojo Keji, 2017**

**Akori Oro: Iberu Olorun** – Apa Keji

**Eko Kika: Romu 3: 9-18**

Ao tesiwaju ninu eko yi nigbati ao menuba wipe ohunkohun ti Olorun ba se yio wa lailai: a ko le fi ohun kan kun u, beli a ko le mu ohun kan kuro ninu re; Olorun si se eyi ki enia ki o le ma beru re **Oniwasu 3: 14**. Olorun ninu akainiye-ogo ati ola-nla re se afihan ajulo fun awa eda-enia ki a le ma beru re, toripe ohun gbogbo ti o ba se je akotan, atipe enia ko le ti owo-bo. Kini de ti o ko beru Olorun fun idi eyi?

**Ko bi a ti nberu Olorun**

Enia ni lati ko bi a ti nberu Olorun, ki nwon si ma huwa gegebi iberu Olorun ti won ti ko, ki awa enia ba le wu Olorun.

**Oju daradara li etan:** Mo fe ki awa enia mo wipe, etan ni oju daradara atipe ewa yio sa: nitorina mase gbekele won, sugbon beru Olorun ki a ba le fi iyin fun o, ki a si se o logo **Owe 31: 30**. Lati inu ese yi, ao ri wipe oju daradara le tan enia fun igba die; oju daradara ati ewa si jasi asan, nitoripe oju daradara ati ewa kip e. Nitorina beru Olorun ki a le fi iyin fun o.

**Apejo Mimo:** A ni lati ko awon enia ni iberu Olorun, kosi gbodo si itenu-bole, pansaga/agbere, isowo tabi igberega; ni awon apejo mimo ninu ile-ijosin, ile-adura, ati awon ori-oke. Awon isele ibe gbodo fi aye gba iberu Olorun, a si gbodo lo ibe ni ona ti o se itewogba si Oluwa **Deuteronomi 31: 12-13**. Ranti ohun ti Jesu Kristi se ni tempili ti ibe ni Jerusalemu, bi o se le awon ti nta ti won nra jade ninu tempili, ti o si yi tabili awon onipasiparo owo danu: Ti o si nwipe "ile adura li ao ma pe ile mi; sugbon enyin so o di iho olosa" **Matteu 21: 12-13**.

**Beru Olorun ki o si sin ni mimo:** Ikede angeli ti o nwasu ihinrere ainipekun fun awon ti ngbe ori ile aiye, ati fun gbogbo orile, ati eya, ati ede, ati enia: ni pe "E beru Olorun, ki e si fi ogo fun u;nitoriti wakati idajo re de; e si foribale fun eniti o da orun, on aiye, ati okun ati awon orison omi" **Ifihan 14: 6-7**. Foribale fun Oluwa, ki o si sin pelu iberu; e si ma yoti enyin ti iwariri ni iwaju Oluwa **Orin Dafidi 2: 11**. Bi o ba fe ko iberu Olorun, o di dandan ki o foribale fun Oluwa, ki o si sin pelu okan mimo ati eri-okan rere.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

## Iberu Olorun ni iwa bi Kristi

Awon ohun ti ao menuba ni iwa-bi-Kristi ti a ko sinu Bibeli, ti yio mu o beru Olorun: Bi

- Emi Oluwa ba bale o
- Emi ogbon ati oye
- Emi igbimo ati agbara
- Emi imoran ati iberu Oluwa
- Orun-didun re si wa ni iberu Oluwa
- Iwo ko se idajo nipa iri oju re, beni o ki yio dajo nipa gbigbo eti re
- Iwo yio fi ododo se idajo talaka, iwo yio si fi otito se idajo fun awon olokan tutu aiye
- Iwo yio ba fi oro Olorun na awon enia, ti iwo si nfi oro-ete re ba awon enia buburu wi
- Ododo ba je amure egbe re, ti isotito si je amure inu re.

Nigbana ni iwo yio beru Olorun pelu gbogbo okan re **Isaiah 11: 2-5**.

## Awon asiwaju ati awon ti ise akoso/oba ni lati beru Olorun

Gbogbo okan ti o wa ni ipo alase ni lati beru Olorun, nitoripe ki ise ipa tabi agbara nwon ni o gbe won si ipo na, bikose ore-ofe Olorun ni nwon ri gba.

**Awon asiwaju ni lati ko iberu Olorun:** Awon asiwaju esin-igbagbo **ko gbodo ko oro ati ohun asan aiye jo fun ara nwon, besini nwon ko gbodo mu ki awon omo-ijo tabi agbo nwon pada sinu igbekun tabi oko-eru.** Awon oselu ati awon ti won wa ni ipo alase **ko gbodo ko owo-ilu je tabi kin won ko opolopo iyawo/ale jo fun ara won.** Awon oba **ni lati ma ka Bibeli, ki nwon si ma huwa gegebi eko Bibeli ti nwon ka, ki nwon ba le ko ati beru Oluwa Olorun nwon, lati ma pa ofin ati ilana Oluwa mo; ki nwon si ma se won Deuteronomi 17: 15-19**.

**Awon alakoso ni lati se akoso pelu iberu Olorun:** Ni awon ojo ikehin oba Dafidi ni ile alaaya. Emi Oluwa soro nipase re; oro Oluwa si mbe li ahon re, o wipe enikeni ti nse alakoso enia lododo, ti nsakoso ni iberu Olorun; yio si dabi imole owuro nigbati orun ba la …. **2 Samueli 23: 2-4**. Oba-koba ti o ba nse isakoso pelu aisododod, ti o si nfi ara ni ara-ilu ti lodi si ipo-ola na; iru awon wonyi ko beru Olorun.

**Awon onidajo ni lati beru Oluwa:** The judges must take heed in whatever they

are doing, they must think carefully before pronouncing judgment, because they are not judging for mortals, but for the Lord. Therefore they must not judge to please people, but to please God and He will be with them when they render the verdict in each case. Furthermore they must fear the Lord and judge with integrity, because the Lord our God does not tolerate or condone injustice, partiality or taking of bribes **2 Kronika 19: 6-7**. Therefore, the judges must always act in the fear of the Lord, with faithfulness, loyal and blameless heart **2 Kronika 19: 9**.

## Beru Olorun ki ise eran-ara ni ki o beru

Olorun nikan ni o to beru; o ko gbodo beru eran-ara, sugbon ki o bowo fun enia; ki o si teriba fun gbogbo ajunilo. Bowo fun gbogbo awon ti owo ye fun, sugbon fi eru fun Oluwa; beru re ni gbogbo ona re, besini yio dara fun o.

**Mase beru enikeni ayafi Olorun nikan:** Bibeli wipe "Oluwa ni imole mi ati igbala mi; tali emi o beru? Oluwa li agbara emi mi; aiya tali yio fo mi" **Orin Dafidi 27: 1**. Mase beru enia, sugbon bowo fun won; mase foiya eleran-ara sugbon teriba fun won. Arugbo-ojo ti o ju gbogbo eda enia lo, ti a npe ni Olorun nikan ni a gbodo beru. Niwon igbati o ba ti fi igbekele re sinu Olorun ti o si beru re, o ko gbodo beru enia, nitoripe eleran-ara kole se nkankan fun o **Orin Dafidi 56: 4, 118: 6**. Ranti ese Bibeli ti o wipe "E ma foiya awon eniti ipa ara, sugbon ti nwon ko le pa okan: sugbon e kuku foiya eniti o le pa ara ati okan run li orun apadi" **Matteu 10: 28**. Fun idi eyi mase beru; enia ko le se ohunkohun si o laisis imotele Oluwa, sugbon beru Oluwa ti mbe ese awon baba wo lara awon omo, ati lara irandiran won **Eksodu 20: 5**. Se ife Olorun ni gbogbo igba, ki o si beru On nikan.

**Mase beru orisa tabi irumole:** Ara ninu Oluwa, e mase beru orisa tabi irumole awon enia ile ibiti e ngbe, sugbon e gba ohun Oluwa gbo, ki e si beru re **Onidajo 6: 10**. Ni igbekele ninu oro Olorun ti o wipe "Awon olorun ti ko da orun on aiye, awon na ni yio segbe loju aiye ati labe orun wonyi" **Jeremiah 10: 11**.

**Mase te enia lorun lati kolu Olorun:** Ki yio dara fun enia buburu, beni ki yio fa ojo re gun ti o dabi ojiji, nitoriti nwon ko beru Olorun **Oniwasu 8: 13**. Mase si lara awon enia buburu ti ko beru Olorun, sugbon ti nwon beru eleran-ara; mase si lara awon ti nwon ntitori ati te enia lorun, kolu Olorun; ki o ba le dara fun o ni gbogbo ojo aiye re.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Keedogun: Osu Kerin Ojo Kesan, 2017**

**Akori Oro: Iberu Olorun** – Apa Keta

**Eko Kika: Romu 3: 9-18**

Ao tesiwaju nipa oro lori awon ofin Oluwa ti o di'romo iberu Olorun.

**Awon ofin Oluwa**

O je ojuse awon kristiani lati ma kiyesi awon ofin Oluwa, pataki-julo awon ofin ti o ro'mo iberu Olorun, ki nwon ba le gbe igbe aiye alafia.

**Mase ni enia lara:** Beru Oluwa Olorun re, mase se ai'da si omonikeji. E mase re ara nyin je, sugbon e beru Olorun. Iwo ko gbodo ni enikeji re lara, sugbon o ni lati beru Olorun ni iwe mimo wi **Lefitiku 25: 17**. Se afihan wipe o beru Olorun nipa ai-siwawu si awon enia. Nitorina iwo ko gbodo sika si alejo, beni iwo ko gbodo ni i lara ni onakona **Ekosdu 22: 21**. Fetisile si ohun Oluwa re, nipa aini enikeni lara, ki o si beru Olorun re.

**Mase akoso pelu iroro:** Mase je on'roro si awon enia, beni o ko gbodo fi owo-lile se akoso, sugbon o gbodo beru Olorun. Enikeni ti o ba nfi ikanra tabi iroro se akoso awon enia ko beru Olorun: iru awon enia na, si ti se aigboran si ofin Olorun **Lefitiku 25: 43**. Torina se akoso pelu iwa-pele ati anu, ki o ba le tesiwaju ninu pipa ofin Oluwa Olorun re mo.

**Mase gba owo-ele ati eda:** O ko gbodo gba apoju owo-ele lori gbese ti a je o, sugbon o ni lati beru Oluwa. Bibeli wipe o ko gbodo gba ele tabi eda lowo arakunrin re; sugbon beru Olorun re **Lefitiku 25: 36**. Beru Olorun, iwo ko gbodo fi owo re fun arakunrin re li eda, tabi ki o win li onje fun asanle **Lefitiku 25: 37**. Ranti wipe o san lati ni die pelu iberu Oluwa, ju isura pupo ti on ti iyonu ati wahala **Owe 15: 16**.

**Mase sote si Olorun:** Ohun ti o dara-ju ti o le sele si enia ni ki o beru Oluwa, ki o si gboran si ohun re; besini ki o mase tapa si awon ofin Oluwa. Nigbana ni yio dara fun iru awon enia na **1 Samueli 12: 14**. Awon omo Israeli sote si Oluwa ni inu aginju, lehin igbani-yanju Josua ati Kalebu **Numeri 14: 6-9**. Irin-ajo ogoji ojo, di ogoji odun ninu aginju. Gbogbo awon enia ti o je omo ogun odun ati jubelo ni aika Josua ati Kalebu ni nwon ku ninu aginju **Numeri 14: 26-35**. Olorun ma

nrerin idamu awon olote, yio si se efe awon alaigboran nigbati iberu nwon ba de: nitori nwon korira imo, besini nwon ko beru Olorun **Owe 1: 24-27**.

**Ko ibi sile, ki o si ni'fe aladugbo re:** Ni ife aladugbo re gegebi ara re. Mase je isubu fun awon enia tabi wa isubu awon enia, besini o ko gbodo je okun-fa ogbe tabi oju-ogbe si ara awon enia. Se dede ni gbogbo ona re, gegebi ese ti o wipe "Iwo ko gbodo bu aditi, tabi ki o fi ohun idigbolu siwaju afoju, sugbon ki iwo ki o beru Olorun re: Emi li Oluwa" **Lefitiku 19: 14**. O ko gbodo bu elomiran, o ko gbodo lu enia tabi ki o je okun-fa ikose awon enia. Bi Olorun ba le jeri Jobu wipe oloto ati eni-idurosinsin li ise; wipe Jobu beru on Olorun, o si korira iwa buburu. Iwo na ni lati ni ife awon aladugbo re, ki o si ma huwa idogba ati aisi-iyanje si gbogbo enia, ki Olorun ba le jeri wipe o beru on **Jobu 1: 8**. Ara ninu Oluwa itan wo ni awon orun yio so nipa tiwa, torina e jeki a ni ife aladugbo wa, ki a si beru Olorun ki akoko to koja lo.

**Mase ro wipe o je ologbon:** Opolopo enia ninu aiye loni ni nwon nro wipe awon je ologbon, atipe nipase ogbon awon ni awon se ni aseyori lori awon adawole won. Ni ile-ibi mi, a ma nso oro wipe "Bi ologbon ba se bi eniti o go, yio pe pelu ogbon na" oro yi si wa ni ibamu pelu oro inu iwe mimo, ti o wipe "Mase ologbon li oju ara re; beru Oluwa, ki o si kuro ninu ibi" **Owe 3: 7**. Jeki iberu Olorun re je lotito, ni aisi agabagebe pelu re. Opolopo enia ninu aiye loni ni nwon ni idi-miran ti nwon fi beru Olorun, yala nitori awon ohun ti Olorun ti se ninu aiye nwon ni, tabi nitori awon ohun ti nwon nreti lati odo Olorun. Olorun jeki Satani mo wipe on se asise nigbati o wipe "Jobu ha beru Oluwa li asan bi?Iwo ko ha ti sogba yi i ka, ati yi ile re ati yi ohun ti o ni ka ni iha gbogbo? Iwo busi ise owo re, ohunosin re si nposi i ni ile" **Jobu 1: 9-10**. Jeki iberu Olorun re je ojulowo. Beru Olorun laijepe nitori oro-aiye tabi awon ohun asan aiye yi: sugbon beru re, nitori ibiti iwo yio ti lo isinmi aiyeraye re.

**Ni iteriba:** Bibeli wipe "E ma teriba fun ara nyin ni iberu Olorun" **Efesu 5: 21**. Enyin aya e fi otito teriba fun awon oko nyin, gege bi fun Oluwa. Enyin ipere, e teriba pelu irele fun awon agba. Enyin osise, e ma teriba lojulowo fun awon ti nwon ni ile-ise; besini ki gbogbo enia ma teriba pelu iberu Olorun fun awon alase ati olori ti nwon ba nsise gegebi ilana Oluwa. **Efesu 5: 22, 1 Peteru 5: 5, 2: 13**. O ni lati mo ninu okan re wipe, Olorun ki igbe ibi julu-julu atipe imo-toto ati sise nkan leselese ni ofin ninu orun. Nitorina, e ma se ohun gbogbo teyeteye ati leselese pelu iberu Olorun **1 Corinthians 14: 40**.

**<u>Bowo fun awon agba ati arugbo:</u>** Bibeli wipe "Bowo fun baba on iya re: ki ojo re ki o le pe ni ile ti Oluwa Olorun re fi fun o " **<u>Eksodu 20: 12, Deuteronomi 5: 16</u>**. Ibowo yi koni lati je ti awon obi re nikan, bikose fun gbogbo awon agba ati awon ajunilo. A kowe re wipe "Ki iwo ki o si dide duro niwaju ori-ewu, ki o si bowo fun oju arugbo, ki o si beru Olorun re: Emi li Oluwa" **<u>Lefitiku 19: 32</u>**. Ni igbakugba ti o ba nbowo fun ewu-ori, ise ni o nbowo fun Oluwa Olorun re; Arugbo-ojo, arugbo ti o ju gbogbo arugbo lo. Nigbati o ba si nse alai-teriba fun awon agbagba, nse ni iwo nse alai-teriba fun Olorun; ti o si nri fin i. Nitorina, beru Olorun ki o si bola fun, besini on na yio bola fun o **<u>1 Samueli 2: 30</u>**. Ri daju pe o ko gbagbe lati bola fun Olorun, ki o si ma beru re ni ibigbogbo ati ninu ohun gbogbo ni gbogbo ojo-aiye re. Oro yi wa ni ibamu, o si se oni-gbowo fun ese Bibeli ti o wipe "E san ohun ti o to fun eni gbogbo: owo-ode fun eniti owo-ode ise tire: owo-bode fun eniti owo-bode ise tire; **eru fun eniti eru ise tire; ola fun eniti ola ise tire**" **<u>Romu 13: 7</u>**. E san eru ati ola fun Olorun, ki o ba le dara fun nyin. Fun idi eyi: e bowo fun gbogbo enia. E fe awon ara ninu Oluwa. E beru Olorun. E bowo fun oba ati awon alase **<u>1 Peteru 2: 17</u>**.

**<u>Nigbati itura ba de, mase si iwa hu:</u>** Lotito Olorun yio fun o ni ore-ofe, besini yio sanu fun o, nigbati itura ba de, ti awon ala re si wasi imuse; mase si iwa hu tabi ki o lo irun-iwaju mo ti ipako; sugbon tesiwaju ninu iberu Olorun. Kiyesara ki awon ohun didan ati ohun asan aiye yi maba mu o hu iwa-kiwa **<u>Josua 24: 13-14</u>**. Ri daju wipe iberu Olorun ko si lo kuro ninu aiye re nigbati ero-ngba re bati wa si imuse. Nigbana ni iwo yio mo iberu Oluwa, iwo yio si ri imo Olorun ti yio mu o duro lai-yese ni gbogbo igba iwa-laaye re **<u>Owe 2: 5</u>**.

**<u>Sin Olorun, ki o si beru re:</u>** "E beru Oluwa, ki e si fi gbogbo okan nyin sin i lododo: nje, e ronu awon ohun nlanla ti o se fun nyin" E mase gbagbe gbogbo ore Olorun ninu aiye nyin titi di akoko yi **<u>1 Samueli 12: 24</u>**. Jeki o wa ninu okan re pe iberu enia ni imu ikekun wa: sugbon enikeni ti o gbeke re le Oluwa li ao gbe leke **<u>Owe 29: 25</u>**. Niwon igbati o je wipe iberu enia ni nfi adari-hurun sinu panpe, beru Olorun ki o si sin.

**<u>Araiye ni lati beru Olorun:</u>** A kowe re wipe Olorun tobi, o si ni iyin pupopupo: on li a ni lati beru ju gbogbo orisa lo. Titobi ni Oluwa, o si ye fun iyin. On ni a ni lati beru ju ohun gbogbo ti mbe ninu orun ati lori ile aiye lo **<u>Orin Dafidi 96: 4</u>**. Olorun li o ni iberu gidigidi ni ijo enia mimo, on ni a gbodo beru-julo, nitoripe o ni ibuyin-fun lati odo gbogbo awon ti o yi i ka **<u>Orin Dafidi 89: 7</u>**. Gbogbo aiye gbodo beru Oluwa: ki gbogbo araiye ki o ma wa ninu eru re **<u>Orin Dafidi 33: 8</u>**.

## Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

### Ose Kerindinlogun: Osu Kerin Ojo Kerindinlogun, 2017

### Akori Oro: Iberu Olorun – Apa Kerin

### Eko Kika: Romu 3: 9-18

Ao tesiwaju ninu eko yi, nigbati ao soro nipa awon ere ti ao fifun gbogbo awon ti o ba beru Olorun.

### Awon ere iberu Olorun

Iberu Olorun ti o ni kise lasan, nitori Olorun yio fun o ni ekun-rere ere nitori ti o beru re. Opo lara awon anfani iberu Olorun ni iwonyi: Olorun tikarare yio ko o nipa oro re, debipe iwo yio ni imo ti o peye, lati yan ona ododo ti o lo si ibi iye: iwo ki yio si yan ona iparun ti iyorisi iku **Orin Dafidi 25: 12**. Bi o ba nfe itoni Olorun ninu gbogbo ero ati ipinnu re, beru Olorun lojulowo.

**Olorun yio ma so o:** Olorun yio se oju re ki o mole si o lara fun rere. Olorun yio ma se oluso re, ni gbogbo akoko iwa-laaye re, titi ti ife re yio fi wasi imuse ninu aiye re **Orin Dafidi 33: 18**. Niwon igbati o ba ntesiwaju ninu iberu Olorun; oju Oluwa yio ma wa lara re, yio si ma so o. Nigbati isoro ba dide si o, Olorun yio wa pelu re, yio si je iranlowo ati asa fun o. Olorun koni jeki isoro na ba aiye re je, tabi ni ipa-buburu titi-lai lori re, bi o ba le beru Oluwa Olorun re **Orin Dafidi 115: 11**. Bi o ba nfe iranlowo ati ade-abo Oluwa, o ni lati beru re: nitoripe ninu iberu Oluwa ni igbekele ti o lagbara wa, yio si je ibi-abo fun awon omo re. Enikeni ti o ba beru Olorun ni i ile-iso ti o lagbara, yio si je ibi-isasi fun iru-omo nwon **Owe 14: 26**. Beru Olorun, bi o ba nfe abo ti o peye fun iwo ati awon omo re.

**Olorun yio gba o:** O je olori-ire bi o ba wa lara awon ti o beru Olorun, nitoripe yio gba o, lowo awon ota re gbogbo. Olorun yio gba o kuro ni owo-agbara awon abinuku re, yio si gba o la kuro lowo awon okunkun **2 Awon oba 17: 39**. Olorun yio pase fun awon angeli lati rogba yi o ka, ki nwon si gba o lowo awon ti o korira re. Enikeni ti o ba beru Olorun, awon angeli yio se oluso re, nwon yio yi iru eni be ka, nwon yio si se olu-gbeja re **Orin Dafidi 34: 7**. Fun angeli Oluwa lati sunmo o, ki nwon si gba o ni igba iponju ati wahala re, o ni lati beru Olorun.

**Olorun yio fun o ni onje oojo, yio si fi idi majemu mule ninu aiye re:** Asiri Oluwa wa pelu awon ti o beru re, yio si fi won mo majemu re. Ipinnu Olorun je ti awon ti o beru re, nitoripe yio fi asiri ati ero re han fun nwon **Orin Dafidi 25: 14**.

Idapo timotimo pelu Olorun je ti awon ti o beru re, yio si fi majemu re mule ninu aiye won. Olorun yio pese onje-oojo fun won ni ona irorun ti koni jeki oruko re ti o li ogo di isoro-odi si **Orin Dafidi 111: 5**. Ri daju wipe o beru Olorun, ki o ba le fi idi majemu aiyeraye mule ninu aiye re.

**Iwo ki yio se alaini:** Bibeli wipe, " E beru Oluwa, enyin enia re mimo: nitoriti ko si aini fun awon ti o beru re" Enikeni ti o ba beru Oluwa ki yio se alaini ohun kan, sugbon ao fi ire te won l'orun **Orin Dafidi 34: 9**. Bi o ba fe ki Olorun fun o ni awon ohun kosemani, ki o si ba aini aiye re pade, beru Olorun. Nigbana ni Olorun yio pese ni kikun fun gbogbo aini re, gegebi oro re ninu ogo nipase Kristi Jesu **Filippi 4: 19**.

**Olorun yio yo'nu si o, yio si sanu re:** Bi baba ti ise iyonu si awon omo, beli Oluwa nse iyonu si awon ti o beru re. Oluwa je baba fun awon omo re, O si nse iyonu ati iseun-ife si awon ti o beru re **Orin Dafidi 103: 13**. Nitoripe bi orun ti ga si ile, beli anu Olorun tobi si awon ti o beru re. Ife-aisetan ati ife-ailopin Olorun fun gbogbo awon ti o beru re, dabi iwon-giga awon orun si ori ile-aiye **Orin Dafidi 103: 11**.

**Olorun ni inudidun si o, yio si mu ife re se:** Inu Oluwa dun si awon ti o beru re, yio si se inudidun si enikeni ti o beru re. Lotito, o ni inudidun si awon ti o beru re, si awon ti nse ireti anu re **Orin Dafidi 147: 11**. Beru Oluwa, ki o le se oju-rere si o. Igbese ti o ni lati gbe ki ife-okan re ba le wasi imuse, ni ki o beru Olorun. Iwe mimo wipe, Olorun yio mu ife awon ti mberu re se: yio gbo igbe won pelu, yio si gba won **Orin Dafidi 145: 19**. Bi o ba nfe ki Olorun mu ife-rere re se, ki o si te o lorun pelu ire-gbogbo ninu aiye, o ni lati beru re.

**Igbala ati ogo:** Agbara-igbala Olorun wa nitosi awon ti o beru re, besini titobi ola-nla re yio ma gbe ile won. Awon ti o beru Oluwa ni idaniloju wipe igbala re sunmo won, ogo re yio si ma gbe ile won **Orin Dafidi 85: 9**. Beru Olorun, ki o le fi igbala re han ninu aiye re, ki o si fi ogo kun ile re ati orile-ede re.

**Olorun yio fi ire sawari re:** Olorun ti pese opolopo awon ohun-iyanu ti yio fifun awon ti o beru re. Olorun ni aka-nka-tan ire ti o to-jo fun awon ti o beru re: yio fi se awon ti o wasi odo re fun abo ati ibukun, li oso loju araiye. A kowe re wipe, "Ore re ti tobi to, ti iwo fi sura de awon ti o beru re: ore ti iwo ti se fun awon ti o gbekele o, niwaju awon omo enia" **Orin Dafidi 31: 19**. Beru Olorun fun ore-nla re.

**Emi-gigun:** Ohun kan ti a le fi segun emi-kukuru ni iberu Olorun. Iberu Oluwa ni nmu ojo enia gun bi owo-aso. Iberu Olorun ni ona tabi ipa ti iyorisi emi-gigun.

Iberu Oluwa mu ojo gun: sugbon odun enia buburu li ao se kuru **Owe 10: 27**. Iwo ati iru-omo re ni lati beru Oluwa ni gbogbo ojo aiye yin, nipa pipa ofin ati ilana re mo, ki e ba le gbe ile-aiye pe titi. Bi iwo ati awon omo re ba beru Oluwa Olorun yin niwon igbati e wa laaye, bi e ba npa ilana ati ofin re mo; igbana ni ojo yin yio pe lori ile-alaaye **Deuteronomi 6: 1-2**. Bi o ba nfe ojo-gigun ati emi-gigun, beru Olorun.

**Olorun yio busi fun o pelu oro, ola, ati iye:** Ere irele ati iberu Oluwa li oro, ola ati iye. Irele ati iberu Oluwa ni isoni di oloro ati olola, ti o si funni ni iye ainipekun **Owe 22: 4**. Fun idi eyi Oluwa Olorun pa a lase fun wa, lati ma se gbogbo ilana re, ki a si ma beru re; ki o ba le tesiwaju lati ma bukun wa, ki o si pa wa mo laaye, gegebi o ti nse titi di oni. Ojuse wa ni lati pa awon ilana Olorun mo, ki a si beru re; fun ire wa nigbagbogbo, ki o le pa wa mo laaye, bi o ti ri li oni yi **Deuteronomi 6: 24**. Ibukun ni fun okunrin na ti o beru Oluwa, iru-omo re yio lagbara ni aiye. Iru-omo enikeni ti o ba beru Oluwa, ti inu re dun jojo li ofin re, ni yio se aseyori ni ibigbogbo; nwon yio si je alagbara ni ile won **Orin Dafidi 112: 1-2**. Ibukun ni fun gbogbo eniti o beru Oluwa; ti o si nrin li ona re. Bi o ba beru Oluwa, o di eni-ibukun **Orin Dafidi 128: 1**. Olorun yio busi i fun awon ti o beru re, pelu agbon-magbe ibukun, ati ewe ati agba won ni yio bukun fun **Orin Dafidi 115: 13**. Kiyesi i, pe beli ao busi i fun okunrin na, ti o beru Olouwa **Orin Dafidi 128: 4**.

**Yio dara fun o:** Labe botiwu-kori emi mo wipe yio san gidigidi fun awon ti o beru Olorun. Lotito bi elese tile se ibi nigba ogorun, ti ojo re si gun, sugbon nitoto, **emi mo pe yio dara fun awon ti o beru Olorun,** ti o beru niwaju re **Oniwasu 8: 12**. Beru Olorun ki o ba le dara fun o, ni gbogbo ojo aiye re.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Ketadinlogun: Osu Kerin Ojo Ketalelogun, 2017**

**Akori Oro: Iberu Olorun** – Apa karun

**Eko kika: Romu 3: 9-18**

Niwon igbati a ti menuba awon anfani, ati awon ileri Olorun fun awon ti o beru re; ara ninu Oluwa, e jeki a we ara wa mo kuro ninu eeri ti ara ati eeri ti emi, ki a si je pipe ninu iwa mimo; nipase iberu Olorun. Nitorina, ojuse wa ni ara ninu Oluwa, lati we ara wa mo kuro ninu gbogbo egbin ti ara ati ti emi: ki a si ma so iwa mimo di pipe ninu iberu Olorun **2 Korinti 7: 1**. Olorun ninu opo iyo-nu re setan lati dariji enikeni ti o ba ronupiwada lotito; ki awa eda-enia ba le ma beru re. Olorun fi idariji-ese lo awa omo adari-hurun, ki a ba le ko lati ma beru re. A kowe re wipe "Nitori idariji wa lodo re, ki a le ma beru re" **Orin Dafidi 130: 4**. Beru Oluwa, nitoriti o ti mura-tan lati dari awon ese re jin o. Nje enikan mbe ti ko ni ese? Bi ko ba si, o di dandan ki araiye beru Olorun.  Tani ki yio beru re Oluwa, Iwo oba awon oba ati oba awon orile-ede? Iwo nikan ni o ye lati beru. Toripe, larin gbogbo awon ologbon enia ni awon orile-ede ati awon ijoba won, kosi eniti o dabi re. Bibeli wipe Tani ki ba beru re, Iwo oba orile-ede? Nitoripe, eto ti o to si Iwo Olorun ni, besini oye tabi apele yi je tire nikan. Larin gbogbo awon ologbon asiwaju ni agbaiye ati awon ijoba won, ko si eniti o dabi Iwo **Jeremiah 10: 7**.

## Awon idi ti a fi gbodo beru Olorun

Ao se ayewo awon apejuwe ninu Bibeli, eyiti o le mu ki awon enia beru Olorun pelu gbogbo okan won.

**Ao bewa wo lati mo daju wipe a beru Olorun:** Olorun ni lati se ayewo tabi idanwo fun wa lati mo daju wipe a beru on; ni igba miran O le gba Esu la'ye lati dan wa wo, ki a ba le fi idi re mule wipe a beru Olorun atipe a koni se Olorun tabi ki a da'le majemu re. A le dan o wo ni orisirisi ona ti o yato si ti awon enia ti o yi o ka. Idanwo tire si le yato si bi Olorun se dan awon omo Israeli wo ninu Bibeli, nigbati o sokale si ori-oke Sinai. Awon enia beresini jaiya, won si nfo'ya, nigbana ni Mose wipe "E  ma beru: nitoriti Olorun wa lati dan nyin wo, ati ki eru re ki o le ma wa li oju nyin, ki enyin ki o mase se **Eksodu 20: 18-20**. Se o ti gbaradi fun idanwo? Yala o fe tabi o ko fe, ao dan o wo lati fi idi re mule wipe o beru Olorun; o si ti se-ra fun ese.

**Beru Olorun ki ajalu maba de ba o:** Nigbati oba Assiria ko awon ajoji wa lati ma gbe ilu samaria, awon ajoji wonyi beresini gbe ilu Samaria; sugbon won ko beru Oluwa, beni won ko sin i. Nitorina Oluwa ran awon kiniun sarin won, ti o pa ninu won. Won rohin awon isele-buburu yi fun oba Assiria, oba si ran okan lara awon alufa ti a ko ni igbekun si won, lati ko won ni bi a ti nberu Oluwa. Ni igbana ni ipa-ni awon kiniun yi to dopin **2 Awon oba 17: 24-28**. Bi o ko ba fe ki ajalu sele si o tabi ki ibi subu lu o, ko bi a ti nberu Olorun lati wakati yi lo.

Beru Olorun, masi se kun si Olorun tabi soro odi si Eleda re, ki Olorun ti o fe o, pelu ife-inu-rere, maba yipada lati se o ni ibi. Olorun pese onje jije **Eksodu 16: 6-15** ati omi mimu **Eksodu 17: 1-7** fun awon omo Israeli ninu irinajo won ni aginju. Olorun binu si awon omo Israeli, nitoriti won nhu iwa-kiwa, besini won ko beru re. Nigbati awon enia na si ba Olorun ati Mose so o, Oluwa ran ejo amubina si awon enia na, nwon si bu awon enia na san; opolopo ninu awon omo Israeli si ku **Numeri 21: 5-6**. Bi o ko ba fe ki iru ohun ti o sele si awon omo Israeli sele si o, mase se a'so tabi soro-odi si Olorun ati awon eni-mimo re; sugbon huwa-rere ni gbogbo akoko ti iwo yio lo ninu aiye, ki o si se ohun gbogbo pelu iberu Olorun **1 Peteru 1: 17**. **Huwa-rere ni gbogbo akoko iwa-laaye re ninu iberu Olorun, ki Oluwa ti o ti nsanu fun o, ti o si nyo-nu si o, maba yipada lati pa o run.**

**Fihan wipe o beru Olorun nipase ise re:** Olukuluku alaaye okan ni lati fihan wipe won beru Olorun, ki won to le ri awon ohun rere gba lati odo Oluwa. Abrahamu so di mimo wipe on beru Olorun, nigbati Olorun wi fun pe ki o mu Isaaki omo re, lati fi ru ebo- sisun si on **Genesisi 22: 1-2**.

- **A busi fun Abrahamu pelu ase isodi-pupo ola-nla ati ase isodi-pupo fun rere** " Pe ni bibukun emi o bukun fun o, ati ni bibisi emi o mu iru-omo re bisi i bi irawo oju-orun, ati bi iyanrin eti okun"
- **Iru-omo Abrahamu di asegun** "iru-omo re ni yio si ni enubode awon ota won"
- **Abrahamu si jogun majemu aiyeraye** "Ati ninu iru-omo re li ao bukun fun gbogbo orile-ede aiye" **Genesisi 22: 15-18**.

Bi iwo na ba beru Oluwa, iwo yio ri ire ti o koja oye enia gba lati odo Olorun.

**Awon iyagba ri ire gba:** Awon iyagba ko pa awon omo-okunrin ti awon obinrin Heberu mbi, nigbati won ba ngbebi fun won, gegebi ase Farao oba Egipti; nitoriti won beru Olorun **Eksodu 1: 15-17**. Fun idi eyi, Olorun se rere

fun awon iyagba na, o fun won ni ebi tiwon, o si kole alayo fun won, nitoriti won beru Oluwa **Eksodu 1: 20-21.** Bi o ba feki Olorun se rere fun o , bi o ba nfe ki Olorun fun o ni eso-inu, ki o si fun o ni ile ti o kun fun alafia; beru re nisisiyi.

**Iberu Olorun yio yanju awon isoro re:** Iberu Olorun nikan ni o le yanju isoro re. Ko eko lati ara obinrin-opo ti o je opolopo gbese, sugbon nitoriti o beru Olorun, ayipada de ba igbe-aiye re; o kuro ni onigbese, o si di eniti asiri re mbo **2 Awon oba 4: 1-7**. Bi o ba nfe ki ayipada nla de ba aiye re, mase siyemeji, sugbon beru Olorun ki a ba le yanju awon wahala re ni kiakia.

**Jobu ri oju-rere ati ibukun ti ko legbe gba:** Bibeli jeri wipe Jobu se oloto, o duro sinsin, o beru Olorun, o si korira iwa buburu **Jobu 1: 1**. Esu fi awon ohun ti o ni danwo, sugbon ko fi Olorun sile tabi ki o kehin si Eleda re. Olorun bukun Jobu pelu emi-gigun ati ilopo-meji awon dukia ati awon ohun-ini ti o ti ni teleri **Jobu 42: 10-16**. Bi o ba nfe ore ti ko ni igbimo ati ibukun ailegbe, mase mu amulu-mala, sugbon beru Olorun.

Lakotan, awon ti won beru Oluwa nba ara won soro nigbakugba, Oluwa si teti si i, o si gbo ohun ti won nwi. A si ko iwe-iranti kan niwaju Oluwa, fun akosile-oruko awon ti won beru Oluwa, ti won mbowo fun oruko mimo re, ti won si nse asaro oruko re **Malaki 3: 16**. Se oruko re mbe ninu iwe-iranti? Bi ko ba si oruko re ninu iwe-iranti, ba Eleda re laja ni kiakia, ki o si gbe igbese lati beru Oluwa.

**Edidi: Deuteronomi 10: 12:** Nje nisisiyi, kristiani, kini Oluwa Olorun re mbere lodo re, bikose **lati ma beru Oluwa Olorun re**, lati ma rin li ona re gbogbo, lati ma fe e, ati lati ma sin Oluwa Olorun re pelu aiya re gbogbo, ati pelu okan re gbogbo?